# AKOKO TI A DÁ FUN ENIYAN

**Oniwasu 3:1-17; 8:11-13; Orin Dafidi 95:1-11; Isaiah 49:7-9; 2 Kọrinti 6:2**

**ẸKỌ 377 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Kiyesi i, nisisiyi ni akokò itẹwọgbà; kiyesi i, nisisiyi ni ọjọ igbala" (2 Kọrinti 6:2).**

**I Akoko fun Ohun Gbogbo**

1 A fi aworan igbesi-ayé eniyan wé ọ̀pọlọpọ awọn nnkan ti o lodi si ara wọn ti o si n ṣẹlẹ, Oniwasu 3:1-8

2 Ọlọrun ti ṣe eto ohun gbogbo lọna ti eniyan yoo fi le ni imọ Oun tikara Rẹ̀, Oniwasu 3:9-14; Orin Dafidi 19:1-4; 40:5; Ifihan 15:3, 4

**II Adehun Ayeraye**

1 Gbogbo aiṣotitọ ti a kò ba ronupiwada rẹ̀ ni a o dá lẹjọ ni ayeraye, Oniwasu 3:15-17; 8:11, 13; 2 Tẹssalonika 1:7, 8; Ifihan 20:11-15

2 Awọn olododo yoo gba ere fun iṣẹ ododo wọn, Oniwasu 8:12; Owe 10:22; Matteu 25:31-40

**III Ifẹ ati Ipe Ọlọrun**

1 Oluwa, Ọlọrun ti o tobi ni O si yẹ fun iyin awọn eniyan, Orin Dafidi 95:1-6; 67:3; Heberu 13:15; Ifihan 7:9, 10

2 Oluwa n beere ọkàn gbogbo eniyan, Orin Dafidi 95:7, 8; Isaiah 49:7-9; 2 Kọrinti 6:2

3 Ki i ṣe gbogbo eniyan ni yoo sin Ọlọrun, Orin Dafidi 95:9-11; 1 Samuẹli 8:7; Luku 19:14

## ALAYE

### Adehun

"A si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẽkanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi idajọ" (Heberu 9:27). Ọlọrun ti fi aṣẹ yi lelẹ o si ti fi idi otitọ yii mulẹ ninu ọkàn ọmọ-eniyan -- otitọ ti ohunkohun kò le nù kuro. Oriṣiriṣi atako ni awọn eniyan ti ṣe si otitọ yii. A ti ronu nipa rẹ̀, a ti sọrọ nipa rẹ̀, a ti kọ iwe nipa rẹ̀, a ti gbà a gbọ́, a ti sẹ́ ẹ, a si ti ṣá a tì; ṣugbọn kò si eyikeyi ninu iṣe ọmọ-eniyan, ero rẹ̀, tabi igbagbọ́ ti o ni ni o le yi otitọ naa ti Ọlọrun ti fi idi rẹ̀ mulẹ pada.

Ni ọ̀na pupọ ni Iwe Oniwaasu fi jẹ́ aworan ero ọkàn ọmọ-eniyan ni ọ̀na àjo rẹ̀ lati mú adehun rẹ̀ ṣẹ pẹlu Ọlọrun. O fi ọ̀pọlọpọ aṣiṣe ati aṣiro ọkàn arinrin-ajo naa hàn gẹgẹ bi o ti n rin ọ̀na igbesi-ayé rẹ̀, titi di akoko igba ti Ọrọ ati ifẹ Ọlọrun mu un wá si ipinnu kanṣoṣo naa ti a sọ ni iba ọrọ kukuru yii pe: "Opin gbogbo ọ̀rọ na ti a gbọ́ ni pe: Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun gbogbo enia. Nitoripe Ọlọrun yio mu olukuluku iṣẹ wa sinu idajọ, ati olukuluku ohun ikọkọ, ibã ṣe rere, ibã ṣe buburu" (Oniwasu 12:13, 14).

### Iran Ti N Kọja Lọ

Sọlomọni nipa ifasẹyin rẹ̀ ri i pé ayé kún fún ipọnju, o si ṣoro lati yé ni. O ri agbara Ọlọrun ti n mú awọn nnkan wá, ti o si n mú wọn duro, ṣugbọn olukuluku awọn nnkan yii ni o dabi ẹni pe agbára iparun kan n tọ̀ lẹyin. A bi eniyan, ṣugbọn ki ikú baa le ri àye ni; lẹyin gbingbin nnkan, lai pẹ ni ikore n tẹle e; ati bẹẹbẹẹ lọ. O dabi ẹni pe òfo ni ayé. O ṣe ni laanu pe awọn eniyan n lo igbesi-ayé wọn lori ilẹ ayé yii lai ṣe akiyesi pe Ọlọrun fi ifẹ ati iṣeun Rẹ̀ yi ayé wọn ká.

Itumọ igbesi-ayé rere ki i ṣe lati maa kiyesi awọn ibanujẹ tabi ayọ̀ wa bi ko ṣe lati maa lò wọn gẹgẹ bi àtẹ̀gùn si igbesi-ayé rere ninu Kristi Jesu. Ojulowo igbesi-ayé rere ni lati mu ọkàn ti Ọlọrun ti tun dá lọ si ayeraye. Bi awọn eniyan ba le din ironu wọn kù nipa awọn wahala ti n dé ba wọn lẹnu iṣẹ ati nipa iwuwo ajaga wọn, bi wọn ba le tubọ ronu nigba pupọ nipa eredi ifẹ ti Ọlọrun fi mu awọn nnkan wọnyii wá, wahala ati laalaa ayé wọn yoo dinku, ayé ki yoo si jẹ́ ohun ti i ṣe awamaridi pupọ fun wọn.

Mimọ̀ pe Ọlọrun ni Ọba ati pe awọn ọmọ-eniyan yoo duro niwaju Rẹ̀ fun idajọ ni ọjọ kan, tó lati mú ki wọn mura silẹ fun ọjọ naa nipa rironupiwada ẹ̀ṣẹ wọn tọkantọkan. “Bi awa ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ ati olododo li on lati dari ẹṣẹ wa jì wa, ati lati wẹ̀ wa nù kuro ninu aiṣododo gbogbo” (1 Johannu 1:9).

**Olufẹ Ayé**

Bi ọmọ-eniyan ba fẹ, Ọlọrun yoo mu un wá si imọ giga nipa ara Rẹ̀ ati iṣẹ Rẹ̀, ṣugbọn ọmọ-eniyan kò fẹ. “O fi aiyeraiye si wọn li aiya, bẽli ẹnikan kò le ridi iṣẹ na ti Ọlọrun nṣe lati ipilẹṣẹ titi de opin.” Tabi ki a sọ ọ ni ọ̀na miiran pe, eniyan nipa ti ara ti lọ jinna kuro lọdọ Ọlọrun to bẹẹ gẹẹ ti ero ayé isisiyii si ti gbà á lọkan kan to bẹẹ ti ero ohun ti o tayọ eyi kò fi le yé e.

Lai si aniani, nigba ti Adamu ati Efa wà ni ipo iwa mimọ́, ṣaaju ki wọn tó ṣubu sinu ẹ̀ṣẹ, wọn ni imọ̀ ti o jinlẹ nipa iṣẹ ati eto Ọlọrun. Ṣugbọn imọ̀ ibi rọpo imọ rere; ibẹru rọpo irẹpọ̀ ati ibarẹ pẹlu Ọlọrun. Iran pupọ kọja ki o to di pe awọn eniyan, (afi iba awọn diẹ) bẹrẹ si ronu nipa iṣeun ifẹ Ọlọrun. Eniyan ni lati mu ifẹ aye kuro ninu ọkàn ti o ba fẹ ni isopọ pẹlu Ọlọrun nitori iwa-bi-Ọlọrun ati ifẹ aye ko le dàpọ. “Nitorina ẹnikẹni ti o ba fẹ lati jẹ́ ọrẹ aiye di ọtá Ọlọrun” (Jakọbu 4:4).

**Idajọ Ododo**

Ogunlọgọ eniyan nipa iwa ati iṣe wọn maa n gbiyanju lati jẹ́ ki awọn ẹlẹgbẹ wọn rò pe eniyan rere kan ni wọn jẹ́. Awọn miiran tilẹ maa n dù ú lọnakọna lati tan awọn aladugbo ati ọrẹ wọn jẹ lati mu ki wọn gbagbọ pe eniyan rere ni awọn jẹ́, bi o tilẹ jẹ pe awọn paapaa mọ̀ ninu ara wọn pe wọn ki i ṣe bẹ ẹ. Irú iwa yii wọpọ laaarin awọn ẹlẹsin, bẹẹ ni o si ti ri lati ayebaye ninu Bibeli. Kò ya ni lẹnu nigba naa ti Sọlomọni fi wi bayii pe, “Ati pẹlupẹlu mo ri ibi idajọ labẹ õrun pe iwa buburu mbẹ nibẹ; ati ni ibi ododo, pe aiṣedẽde mbẹ nibẹ.” Ẹni kin-in-ni ti o kọ́ dán iwa ẹtàn yii wò ni Kaini, ṣugbọn Ọlọrun ṣe idajọ rẹ̀ kiakia. Akani ni ẹlomiran ti o fẹ́ fi ẹ̀ṣẹ pamọ, ṣugbọn lai pẹ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ wa a ri. Nigba pipẹ diẹ si i Ọba Saulu gbiyanju lati mú ki awọn eniyan gbagbọ́ pe olododo ni oun, ṣugbọn o di ẹni ti o pa ara rẹ̀. Awọn Farisi ati Sadusi wá si iribọmi Johannu ṣugbọn Ọlọrun wá wọn ri: “Ẹnyin ọmọ paramọlẹ, tali o kilọ fun nyin lati sá kuro ninu ibinu ti mbọ̀?” (Matteu 3:7). Bibeli kilọ bayii pe “Ki o si dá nyin loju pe, ẹ̀ṣẹ nyin yio fi nyin hàn” (Numeri 32:23).

Nigba pupọ lode oni ni awọn eniyan n huwa buburu dipo eyi ti wọn i ba fi ṣe ohun ti o tọ́, ti o si dabi ẹni pe wọn n mu un jẹ. O ti di àṣa fun awọn eniyan lati maa wi pe kò si ẹni ti o le gbé laye yii lai dẹṣẹ, ṣugbọn ọ̀rọ wọn kò yi Ọrọ Ọlọrun pada. Ibi mimọ́ ni Ọrun jẹ́ sibẹ, awọn ti igbesi-ayé wọn ti yi pada ti wọn si n gbé igbesi-ayé ailẹṣẹ nipa Ẹjẹ Jesu ni yoo gbé ibẹ̀. Nitori ti a n ri iwa buburu nibi ti ododo yẹ ki o gbé wà, ọ̀pọlọpọ ti yi pada kuro lọdọ Ọlọrun, wọn si n pe gbogbo awọn ẹlẹsin ati awọn ti n jẹri iwa-bi-Ọlọrun ni àgàbàgebè. O ṣe danindanin pe irin ati isọrọ awọn Onigbagbọ́ tootọ ni lati jẹ́ alailẹgan ki imọlẹ Ihinrere baa le tàn nitootọ si gbogbo ayé!

Akoko ipinya n bọ̀. “Ọlọrun yio ṣe idajọ olododo ati enia buburu.” A o mu gbogbo aidọgba akoko igba yii kuro. Onidajọ gbogbo ayé yoo ṣa gbogbo awọn eniyan jọ si ibi itẹ Rẹ̀ yoo si ṣe idajọ wọn ni ododo. Ki yoo si agbẹjọro nibẹ lati ro ẹjọ erú to bẹẹ ti yoo fi le yi idajọ po nipa ọrọ didun rẹ̀. Ki yoo si ẹgbẹ́ igbimọ̀ ti a le fi owó rà nibẹ, ṣugbọn olukuluku eniyan ni a o ṣe idajọ rẹ̀ gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀ bá ti ri -- iṣẹ ti Ọlọrun ti kọ sinu iwe Rẹ̀ (Ifihan 20:11-15).

**Mimú Olubori Ere Ije**

Niwọn bi gbogbo awọn nnkan wọnyii ti jẹ́ otitọ, kò ṣoro lati le mọ olubori ere ije ninu ere ije ayé. A fi ohun akiyesi kan siwaju wa nihin: “Bi ẹlẹṣẹ tilẹ ṣe ibi nigba ọgọrun, ti ọjọ rẹ̀ si gùn, ṣugbọn nitõtọ, emi mọ̀ pe … ki yio dara fun enia buburu.” Bibeli fi idi rẹ̀ mulẹ ni ibi pupọ pe ọrọ̀ ti o dabi ẹni pe eniyan buburu ni ki i ṣe oṣuwọn tootọ ti a le fi mọ̀ bi eniyan ti jẹ́ ẹni ayé to tabi ẹni iwa-bi-Ọlọrun. “Yio dara fun awọn ti o bẹ̀ru Ọlọrun.” Lootọ ẹni ti o bá gbẹkẹle Ọlọrun yoo ni iriri idanwo, iyiriwo ati ibawi ṣugbọn o ni apa Ọlọrun lati rọ̀ mọ́ ati Baba Ọrun ti O mọ̀ nipa rẹ̀ lati gbẹkẹle. Igba pupọ ni awọn ẹlẹṣẹ n jiya ju awọn olododo, ṣugbọn oun kò ni ẹni ti o lè ràn án lọwọ tabi ẹni ti o le gbẹkẹle, bi kò ṣe apa ẹran-ara. Awọn eniyan buburu nigba miiran a maa kó ọrọ̀ jọ, ṣugbọn ọrọ̀ tootọ, gẹgẹ bi Oluwa ti fi hàn, ni awọn iṣura wọnni ti a to jọ si Ọrun. Awọn ohun alumọni ayé yoo parun, ṣugbọn awọn iṣura ọrun a maa

wà titi ayeraye. Nigba naa dajudaju, iṣẹgun ikẹyin awọn olododo ni lati jogun Ọrun gẹgẹ bi ile wọn ayeraye, ṣugbọn ẹni ti n rin ọna gbooro yoo ri i pe ọ̀na igbesi-ayé oun lọ taara si iparun.

**Akoko Itẹwọgba**

Ọlọrun alagbara ni Oluwa! Dajudaju Oun ni iyin ati isin eniyan yẹ fun. O ti dá ohun gbogbo, "O si nfi ọ̀rọ agbara rẹ̀ mu ohun gbogbo duro" (Heberu 1:3). Ronu le e lori, eniyan le jẹ ki adura rẹ̀ dé ọdọ Ọlorun, Oun a si fi idahun ranṣẹ!

A fun wa ni apẹẹrẹ ti awọn Ọmọ Israẹli pe wọn gbọ ohun Ọlọrun lati igba-de-igba, wọn si ri ọpọ iṣẹ-iyanu ti O ṣe nitori wọn; sibẹ wọn bi Ọlọrun ninu, wọn dán An wò, wọn si fi oju tinrin aanu Rẹ̀. Fun ogoji ọdún ni Ọlọrun binu si iran naa wi pe, "Nigbagbogbo ni nwọn nṣina li ọkàn wọn; nwọn kò si mọ̀ ọ̀na mi" (Heberu 3:10). O jẹ́ akokò itẹwọgba fun awọn iran Ọmọ Israẹli naa – akoko ti Ọlọrun i ba ti feti si, ti i ba si ti gbọ́ adura wọn, bi o ba ṣe pe wọn gbadura ni ọ̀na ti o tọ́. Nitori ti wọn kọ̀ lati wá Ọlọrun ati lati gbẹkẹle E, eyi mú ki wọn sọ ilẹ ileri nù. Iran awọn Ọmọ Israẹli nì ṣegbe ni aginju.

Bakan naa ni Ẹmi Ọlọrun n bá gbogbo ọkàn ọmọ-eniyan sọrọ lọjọ oni. Ni ọ̀na pupọ ni Ọlọrun ti fi hàn ni ọkàn awọn eniyan pe Oun wà ati pe Oun ni Oluṣẹsan fun gbogbo awọn ẹni ti o fara balẹ wá Oun. Nigba wo ni eniyan ni lati wá Ọlọrun? "Kiyesi i, nisisiyi ni akokò itẹwọgbà; kiyesi i, nisisiyi li ọjọ igbala." Ẹmi Mimọ́ wi pe, "Loni bi ẹnyin bá gbọ́ ohùn rẹ̀, ẹ máṣe sé ọkàn nyin le" (Heberu 3:7, 8). "Ẹ wá Oluwa nigbati ẹ le ri i, ẹ pè e, nigbati o wà nitosi" (Isaiah 55:6), ọjọ n bọ̀ nigba ti a ki yoo le ri Oluwa mọ́. Ẹmi Rẹ̀ ki yoo si sunmọ ọkàn ọmọ-eniyan mọ́ lati mu wọn wá si ọdọ Rẹ̀. Nisisiyii ni Ọlọrun n tẹwọ́ gba eniyan. Akoko isisiyii ni ileri Ọlọrun le ṣẹ lati gbọ́ adura. Kò si ireti ni ọjọ ọ̀la bi ko ṣe fun awọn ti o gbẹkẹle Ọlọrun nihin ati nisisiyii ati awọn ti o lo akoko itẹwọgba wọn pẹlu Ọlọrun.

## AWỌN IBEERE

1 Sọ eredi kan ti Ọlọrun fi yan awọn akokò ati igba.

2 Ki ni o le jẹ́ anfaani kanṣoṣo ti eniyan le ni ni akokò ti a dá fun un ni ayé?

3 Ki ni ṣe ti o fi ṣoro fun ẹda lati moye iṣẹ Ọlọrun?

4 Ki ni ṣe ti o fi jẹ́ ohun ikọsẹ fun awọn ẹlomiran lati ri aiṣedeedee nibi ti ododo yẹ ki o gbé wà?

5 Ta ni yoo ṣe idajọ olododo ati eniyan buburu? Nigba wo?

6 Ki ni ṣe ti ọkàn ọmọ-eniyan fi tẹ̀ si ati ṣe ibi?

7 Ki ni ṣe ti yoo ṣe fi dara fun olododo?

8 Ki ni ṣe ti ki yoo fi dara fun eniyan buburu?

9 Igba wo ni akokò itẹwọgbà eniyan pẹlu Ọlọrun?